# Iwe alaye Thames View Infants

A ki yin kaabọ lati ọdọ gbogbo oṣiṣẹ ati Awọn gomina si ile-iwe ẹlẹyamẹya wa.

Eyi ni awon ọrọ ni ṣoki ti o ṣe Pataki, ti o si wulo fun yin.

Jẹ ki a mọ bi o ba nilo iranlọwọ pẹlu itumọ ede, awa yoo si dari rẹ si ẹnikan ti o le ṣe ọgbufọ fun ọ. Ni ọpọlọpọ igba, awọn obi wa ma nfẹ ran awọn obi miiran lọwọ ni ọna yi.

## Awọn ofin wa




Ni Thames View Infants awa nṣiṣẹ gidigidi lati pese iru awujọ ile-ẹkọ ti nṣe abojuto, ti ndanilaraya, ti o si nṣe atilẹyin, ninu eyiti gbogbo ọmọ ati idile wọn ti ṣe pataki.

Awa npese ayika lati kọ ẹkọ, ni ibiti gbogbo eniyan ti le de ibi ti o ga julọ fun wọn lati de, lai ka ibi ti wọn ti bẹrẹ si.





Awa nkọ awọn ọmọde lati bọwọ fun ara wọn, lati fa ara wọn mọra, ati lati naani ara wọn ati awọn agbalagba papa, ni awujọ ile-ẹkọ ẹlẹyamya wa, ati ninu igbe aye wọn l'ode ile-ẹkọ, nipa jijẹ apẹẹrẹ rere.

Awa nfẹ ki awọn ọmọde gbadun akoko ti wọn ba lo ni ile-ẹkọ, a si ti pese ayika ti o ni aabo, ti o si rọrun, ni ibi ti wọn yoo ti mọ wipe a nse itọju awọn, a si naani wọn, nipa mimu iwa aigbara le ẹlomiran gberu sii ninu aye wọn, nipa nini igbẹkẹle ninu ara ẹni, ati nipa nini agbara lati ṣe ipinnu fun ara wọn.






Awa nlepa lati mu ile-iwe wa fanimọra, a si ro wipe o ṣe pataki ki awọn obi ati olukọ ṣiṣe papọ lati ran awọn ọmọde lọwọ, ki wọn si pese atilẹyin fun wọn.

Nitori pe awa nfẹ lati ran awọn idile wa lọwọ lati lo akoko wọn pẹlu wa lọna to tẹ wọn lọrun julọ, awa tun npese awon iṣẹ kan, eyiti o kọja eyiti ile-iwe ati akoko ile-iwe npese.

extended schools




Bakanna, a wa nṣiṣẹ ni pẹkipẹki pẹlu gbogbo awọn akọṣẹ-mọṣẹ ti o ṣe pataki ni awujọ, awa si le fọwọsọya nipa awọn eniyan ti awa nsisẹ pọ pẹlu. Ninu eyi ni Sue Bramley Children's Centre, Sue Bramley Children's Centre Nursery, Thames View Medical Centre, Christchurch Nursery, Awọn iṣẹ Awujọ, awọn ile-iwe ti o wa nitosi, ati awọn iṣẹ ẹkọ ati atilẹyin awọn alaṣẹ agbegbe yi.

Ni apapọ, a wa npese atilẹyin ti o gbooro fun awọn idile, pẹlu ipese fun awọn "aṣẹṣẹ darapọ".

# Akoko Ile-Iwe



| | | |
|---|---|---|
| **Nursery** | Ọdun 3-4 | 9:10am si 11:40am ati 12:45pm si 3:15pm |
| **Reception** | Ọdun 4-5 | 9:10am si 11:45am ati 1:00pm si 3:15pm |
| **Ọdun 1 & Ọdun 2** | Ọdun 5-6<br>Ọdun 6-7 | 9:10am si 12:15pm ati 1:15pm si 3:15pm |

Jọwọ gbiyanju lati rii daju wipe ọmọ rẹ de l'akoko. Kilaasi kọọkan nbẹrẹ ọjọ wọn pẹlu iṣẹ mimọọka-mọọkọ tabi iṣẹ iṣiro, ọmọ rẹ yoo si padanu ẹkọ ti o ṣe pataki yi bi wọn ba pẹ.





Gbero lati maa de ni bii iṣẹju 5 ki ile-iwe to bẹrẹ, nitori wipe o ko ni fẹ maa duro kiri pẹ titi, paapa julọ ni awọn ọjọ ti o tutu.




A nṣi yara nla ni aarọ ni ojoojumọ fun awọn ọmọde ti o fẹ lati wa si Ẹgbẹ Ounje aarọ, eyiti o bẹrẹ lati 8:30am. Awọn oṣiṣẹ ile-iwe ni yoo bojuto awọn ọmọde. Owo diẹ kan yoo yẹ fun sisan.



Bi o ba pẹ, jọwọ ma ṣe fi awọn ọmọ rẹ silẹ ni ile nitori eyi - yoo wu wa ki ọmọ pẹ ju ki o ma wa rara lọ. Nigbati o ba de ile-iwe, iwọ yoo nilo lati ri oṣiṣẹ ile-iṣẹ, lati rii daju wipe a fi orukọ ọmọ rẹ silẹ fun wiwa ati lati le pese ounjẹ ọsan fun-un.

# Awọn Igbesẹ ile-ẹkọ

Gẹgẹ bi 'ibiti o kọja ile-iwe nikan', a wa npese ẹgbẹ ounjẹ aarọ ṣaaju ile-iwe fun awọn ọmọde, ati ẹgbẹ ti nṣe orișiriși ișẹ ni așalẹ, eyiti awọn ọmọde le maa wa, fun owo kekere. Awọn wọnyi ni imọ igbaradi bọọlu alafesẹgba, ijo ati ẹkọ kọmputa.

A wa tun ni agbaninimọran ti nse alatilẹyin fun awọn obi, ẹniti o nșeto oniruru awọn ẹgbẹ fun awọn obi, ti o si le pese iranlọwọ nipa ọpọlọpọ ișoro ojoojumọ ti awọn idile ndojukọ. Jọwọ wa lati șe ajọpin eyikeyi ișoro ti o le ni, ki wọn to tobi ju.





A wa ni ẹrọ kọmputa/ayelujara kan fun Awọn obi ati Alabojuto ni awọn aarọ Ọjọ aje. Yoo șișẹ lati 9:30-10:30am. Awọn ẹrọ kọmputa ti a le gbe si ẹsẹ (laptops) ti o ni ayelujara ni a ti pese, bẹẹ si ni iranlọwọ wa pẹlu.

Olușakoso imọ ẹrọ wa yoo dahun eyikeyi ibeere ti o nii șe pẹlu PC ti o ni nipa PC ile rẹ. Wa lati baa sọrọ,ohun yoo si sa ipa rẹ lati șe atilẹyin fun ọ,ki o si pese iranlọwọ ti o șe e șe fun ọ.





Lati ran ọ lọwọ lati gba alaye nipa ohun ti o nlo ni ile-iwe ati lati wa ọna abayọ si isoro awọn iwe iroyin ile-iwe ti nsọnu l'ọna ile, awa npese iwe iroyin nipa ișẹ i-meeli. Lati fi orukọ silẹ, ki awọn obi fi orukọ ọmọ wọn ranșẹ nipa i-meeli si:

**Newsletter.TVI@bdcs.org.uk**




Ohun to dara julọ ni ipade 'oju-koju' pẹlu awọn olukọ wa, paapa nigbati a ba nsọrọ nipa kikọ ẹkọ. Șugbọn, o ye wa wipe igbe-aye awọn obi le kun fun ọpọlọpọ ișẹ ati wipe ni ọpọlọpọ igba, o le soro lati ri aaye ati sọrọ. Bi iwọ, tabi ọmọ rẹ, ba ni ibeere kan nipa ișẹ-amurele tabi imọran lori kika iwe ni ile, o le fi i-meeli ranșẹ si:

**HomeworkHelp.TVI@bdcs.org.uk**

Awọn olukọ wa yoo gbiyanju lati dahun ibeere rẹ, tabi șeto ipade kan lati ran ọ lọwọ siwaju sii ni akoko ti o rọrun.

# Wiwa si ile-iwe

O jẹ ohun ti o tọna labẹ ofin pe ki awọn ọmọde wa si ile-iwe deede, ati wipe ki awọn obi tabi alabojuto wọn rii daju wipe eyi waye. A ko faramọ ṣiṣe isansa, a ya fi bi o ba jẹ fun ailera.






Iwọ ko gbọdọ ṣeto isinmi idile ni akoko ile-iwe.

Gbogbo ọjọ ile-iwe wa lo wa lori aaye ayelujara wa:
http://www.thamesview-i.bardaglea.org.uk/diarydates.htm



Ṣugbọn, bi o ba ṣeto lati mu ọmọ rẹ lọ kuro ni ile-iwe fun isinmi kan, o gbọdọ gba fọọmu kan lati ile-iṣẹ ile-iwe ki o si kọọ. Isinmi ti o ju ọsẹ meji lọ ni a ṣe akọsilẹ rẹ bii ṣiṣe isansa ti ko ni aṣẹ.

Bi ọmọ rẹ ko ba fẹ wa si ile-iwe,sọ fun wa. Idi kan le wa fun eyi, awa yoo si ṣiṣẹ papọ lati ṣe iranlọwọ lati tan isoro naa.






Wiwa deede ati dide l'akoko ṣe pataki bi awọn ọmọde yoo ba ṣe aṣeyọri ni ile-iwe.

# Kini mo le ṣe bi ọmọ mi ba nṣaisan?

Bi ara ọmọ rẹ ko ba ya gan, ki wọn ki o wa ni ile lati mu ara wọn pada bọsipọ lori ibusun wọn.








Bi o ba ri bayi, a wa rọọ pe ki o pe (020 8270 4317) tabi fi ọrọ ranṣẹ si (07943 922 655) ile-iṣẹ ile-iwe wa ni 10am ni <u>ojoojumo ati gbogbo ojo ti won ko wa,</u>ki o si sọ fun wa bi wọn ti ṣe e nṣe.

A wa npese ayika ti o ni abojuto ti o si nṣe atilẹyin, a si le jẹ ki ọmọ rẹ tete pada si ile-iwe ni ọpọlọpọ ọna:

- Fifun ọmọ rẹ ni ogun ti o yẹ lati lo (bi o ba pari fọọmu akanṣe kan lati ile-iṣẹ wa)





- Kikiyesi ọmọ rẹ 'ju ti tẹlẹ lọ' nigbati wọn npada bọsipọ ati lati jẹ ki o mọ 'bi wọn ti ṣe nṣe'.



- Bi ba awọn GP ti o wa ni adugbo Thames View Medical Centre sọrọ



- Pipese anfaani yiyan ounjẹ miiran fun wọn ni akoko ounjẹ ọsan (nipa eto akanṣe)



- Ṣiṣe iṣẹ pẹlu rẹ ati ọmọ rẹ bi wọn ko ba farabalẹ tabi bi o ba ni isoro pẹlu mimu wọn wa si ile-iwe ni araarọ
- Riran wọn lọwọ lati ṣiṣẹ de ibi ti o yẹ lori iṣẹ ti wọn ti padanu.

## *Kinni "wiwa ti o dara"?*



Nitori o jẹ ohun ti o le ba ẹkọ ọmọde jẹ bi ko ba wa si ile-iwe deede, **Ijọba ti ṣeto fun gbogbo ile-iwe Ilepa Gbogbogbo fun Wiwa si Ile-iwe, eyiti o jẹ wipe ọmv ile-iwe gbọdọ wa fun 95% ninu gbogbo akoko.**



Eyi tunmọ si wipe, ni ọdun, awọn ọmọde kan padanu ni apapọ ojọ 1 ninu eyi ti o ye ki won wa si ile-iwe l'ọsu kan (tabi ilaji ọjọ ni ọsẹ meji).




Tẹlẹ ni Thames View Infants ọpọlọpọ awọn ọmọde nwa si ile-iwe loojumọ wọn si ni wiwa 100%.



Ni ṣaa kọọkan a ma nfun gbogbo awọn idile ti wọn gba Wiwa 100% ni ẹbun pẹlu "Flower Assembly" eyiti o jẹ akanṣe ti o si gbajumọ.



Ni ṣaa kọọkan, a wa tun maa fun ọmọ kan ti o fi ilọsiwaju ti o lapẹẹrẹ ni wiwa rẹ si ile-iwe fun apapọ ọdun ni kẹkẹ kan.

## *Bawo ni emi yoo ṣe mọ bi wiwa ọmọ mi ti ri?*

Awa nṣiṣẹ ni ajọṣepọ pẹlu awọn idile wa ati, gẹgẹ bii ile-iwe, a wa ntẹsiwaju lati ṣe abojuto wiwa si ile-iwe. Ni aimoye igba, iwọ yoo ti mọ tẹlẹ bi wiwa ọmọ rẹ ba ti lọ silẹ nitori ni akoko kan, a wa yoo ti sọrọ papọ nipa rẹ.

Ni bi a ti maa nṣe, ni gbogbo ọsẹ meji-meji, a wa yoo ṣe ayewo wiwa gbogbo awọn ọmọ wa. Ni ṣaa kọọkan, a wa yoo kọ iwe si obi kọọkan bi wiwa ọmọ wọn ba lọ silẹ ju eyiti a lero ti o si jẹwalọkan ba wọnyi lọ:





- Kere si 95% (aabọ ọjọ kan ṣi ṣiṣe isansa ni aarin ọsẹ meji)
- Kere si 90% (aabọ ọjọ kan laarin ọsẹ kan)
- Kere si 85% (ti o fẹ ẹ to ọjọ kan laarin ọsẹ kan)
- Kere si 75% (ti o fẹ ẹ to ọjọ kan ati aabọ laarin ọsẹ kan)

Bi o ti le jẹ pe wiwa fun '90%' ninu gbogbo akoko jọ wipe o ga, nipa ẹkọ ọmọ, 10% ti o ti padanu le to pipadanu ọdun kan iwe kikọ ni ile-iwe. Nipa fifi eyi to ọ leti nipa lẹta, a le jọ ṣiṣẹ papọ lati ṣe iranlọwọ fun mimu gberu wiwa ọmọ rẹ ati lati jẹ ki o jẹ akẹkọ ti o ṣe aṣeyọri rere



## *Kinni awọn ipa wiwa si ile-iwe ti o lọ silẹ?*




Ki eniyan ma wa deede si ile-iwe le ba ẹkọ ọmọ jẹ. Nipa akojọpọ isiro, awọn ọmọde ti wọn ni wiwa ti o ju 90% lọ ni wọn ma ngba aami ẹkọ ti o dara julọ ti o si ṣe e ṣe ki wọn ri iṣẹ ti o dara ni ọjọ iwaju



Awọn ọmọde ti wọn ni wiwa ti ko dara ma nni isoro pẹlu igbe-aye ni ile-iwe ti wọn si ma a nni isoro lati ni ọrẹ.



Awọn ọmọde ma ni isoro siwaju sii lati 'de ibi ti o yẹ ki wọn de' pẹlu awọn iṣẹ ti wọn ti padanu bi wọn ba nṣe isansa deede.

Ni aimọye igba, o jẹ awọn ọmọde ti kii wa si ile-iwe deede ti wọn maa nka si awọn ti wọn le ni ipalara julọ.





London Borough ti Barking ati Alaṣẹ Agbegbe Dagenham yoo gbe awọn idile ti o ba kuna lati rii daju wipe awọn ọmọ wọn lo si ile-iwe deede lo si ile-ẹjọ, bi o ti jẹ ọran kan. Awọn obi/alabojuto wa ninu ewu ki wọn san owo itanran, tabi ki a gbe wọn lo si ile-ẹjọ, nini lati lọ si awọn kilasi titọju ọmọ tabi ki a ti wọn mọlẹ bi eyi ba lewu to bẹẹ.

A wa ko fẹ ki eyi ṣẹlẹ si eyikeyi idile ọmọ ile-iwe Thames View Infants.



Ile-iwe wa jẹ eyiti o ni abojuto ti ayika rẹ si nmu inu ẹni dun, ti o si ni akojọ awọn ti wọn nduro ti o ga gan, ko si ni dara fun awọn idile ti wọn fẹ ran ọmọ wọn wa si ile-iwe wa, ṣugbọn ti wọn ko le ṣe bẹ nitori ti o ti kun.

## Eto Gbigbani



A wa ni iye nọmba aaye kan ni pato fun ẹgbẹ kọọkan ni ọdun.

Bi ko ba si ibeere siwaju sii fun aaye ni ile-iwe ju nọmba ti o le gba lọ, Alaṣẹ Agbegbe le gba gbogbo awọn ọmọde ti wọn nilo aaye. Ni ibiti awọn ti o fẹ wọle ti ju aaye lọ, Alaṣẹ Agbegbe yoo nilo lati ni abuda gbigbani lati le ṣe ipinnu ẹniti yoo gba aaye ati ẹniti ko ni gba aaye. Abuda gbigbani naa lọ bayi:

1. "Awọn ọmọde ti a Nbojuto".
2. Awọn ọmọde ti wọn ni ẹgbọn ọkunrin tabi obinrin ti wọn nwa si ile-iwe tabi Thames View Junior School.
3. Awọn ọmọde ti wọn ngbe ni agbegbe ti a fun ni gbigbani ti o ga. (Eyi jẹ Ti Adugbo Agbegbe ti Alaṣẹ Agbegbe so bii fifun ni gbigbani ti o ga ju fun ile-iwe kan.)
4. Awọn ọmọde ti wọn ngbe sunmọ ile-iwe julọ ti a ṣe idiwọn nipa ririn ti o wa.




Awọn ọmọde ti a ko pese aaye fun ni yoo ni orukọ wọn lori akojọ awọn ti nduro fun aaye.

# Ilana fun fifi Ẹdun Ọkan han

Olori olukọ tabi Awọn gomina Ile-iwe ni yoo dasi eyikeyi awawi nipa ọrọ ile-iwe.

**Ilana titẹsiwaju:**



**Igbesẹ 1**
Ni ọpọlọpọ igba, yoo dara lati fi awawi kan tabi aibalẹ ọkan le lẹ bi o ti ṣe ṣele pẹlu olukọ kilasi ọmọ rẹ lati ibẹrẹ. Ọpọlọpọ ede aiyede ma nwaye lai ni ero, awọn olukọ wa yoo si feti si ọ, wọn yoo si sa ipa wọn lati tan ọran naa.

**Igbesẹ 2**
Bi o ba si nilo, kan si ile-iwe lati ṣe ajọro isoro tabi awawi rẹ. Ile-iṣẹ ile-iwe yoo ran ọ lọwọ lati ṣeto lati ri Igbakeji Olori olukọ tabi Olori olukọ. Ni ọpọlọpọ igba wọn yoo tan awawi rẹ de ibiti yoo fi ni lọkanbalẹ.





**Igbesẹ 3**
Ṣugbọn, bi o ba fẹ ki awawi rẹ lo ju bẹẹ lọ, kan si Alaga Ẹgbẹ ti nṣe akoso fun ile-iwe, nipasẹ Ile-iṣẹ Ile-iwe.

**Igbesẹ 4**
Bi a ko ba tan isoro/awawi rẹ jọwọ kọ iwe awawi ranṣẹ si Oludari Awọn iṣẹ Awọn ọmọde, ki o si ṣe alaye awọn igbese/iṣẹ ti o ti ṣe tẹlẹ. O jẹ ero Oludari Awọn iṣẹ Awọn ọmọ lati ṣiṣẹ ni pẹkipẹki pẹlu awọn obi, awọn ile-iwe ati Awọn gomina lati gbiyanju lati wa ojutu si awọn isoro.

Awa lero wipe iwọ ri alaye yi bi eyiti o nilo. Ṣugbọn, eyi kan sọ fun ọ nipa awọn nkan ti a nṣe ni ile-iwe wa nikan ni – nitorina jọwọ wa ki o si beere ni Ile-iṣẹ Ile-iwe nipa ohunkohun miiran ti o fẹ mọ, bii aṣọ ile-iwe ati bi o ti ṣe le gba ounjẹ ọfẹ.

Alaye siwaju sii wa lori aaye ayelujara ile-iwe wa ni:
http://www.thamesview-i.bardaglea.org.uk/